AJAKALE ARUN TUN WO'LU EKO




ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO




VOL. IX No. 534. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, AUGUST 24, 1957 KOBO MEJI (2)

# Ajakale Arun Tun Wo'lu Eko

Ni ọsẹ tokọja ni irohin kan wa lati ilu Kano wipe ajakale arun, irufẹẹyiti o ja kakiri agbaiye ninu ọdun 1918 ti nwọn npe ni Influenza, l'o tun wọ'lu Kano nipa awọn ero Mẹka ti o pada de ni nwọn ko arun na wa lati ilu awọn Larubawa.

## OPE NI FUN OLORUN

A gbọ wipe arun na ko iti gbe ọwọ lile iba amodi bi ori fifọ, otutu, ki enia ma sin ara gbigbona ati ki enia ma huko ni arun na fi mba enia ja, larin ọjọ mẹta si marun, bi oluwarẹ ba fi ara si ọwọ, ti o fi ara rẹ bale sile laiko se wahala lọ si ibikibi, yio ri alafia patapata.

Dokita, olutọju ilu sọ wipe enikẹni ti o ba ti ṣakiyesi pe iru amodi wonyi nyọ on lẹnu, ki o tete lọ si ile Alaisan tabi ki ri Dokita fun itọju. A gbọ wipe lati ilẹ Asia ni arun na ti bẹrẹ, o si ti ran de awọn ilu bi Amẹrika, Australia, England ati ilẹ Arabia.

A gbọ wipe awọn to lọ se Hadji ni Mẹka lọdunni ni arun na ba bọ, o si ti han wọn lenmọ nilu Kano; Kaduna, Jos ati Kafanchan. Arun na yọnu de'po ti nwọn fi ti ilewe nilu Abakaliki. Ile Alaisan kun yanturu nilu Kano sugbọn ti ilu Eko na ti goke to ẹgba enia ti amodi na ti kọlu nisisiyi.

*(Wo yoku loju ewe kejo)*

# Oni ile Ife tajo-de



Ẹniti a awo yi ni ọba Alaiyeluwa Ọni Ileṣẹ ẹniti o ti ba wọn lọ silu Oyinbo fun eto ominira ilẹ Nigeria.

Ninu ọsẹ to kọja lọ yi lo ba ọkọ oju omi de si Eko, Alaiyeluwa Ọba Adele Keji ti Eko ni ẹniti o kọkọ wọ inu ọkọ oyinbo lọ ki ọba na wipe ki o kabọ.

Rẹmi Kayode, ti o nṣe ọkan ninu awọn ọmọ Oloye Fani Kayode, amofin pataki lo gbe afọmọ ìgì ọpẹ lọ fi ta Ọba na lọrẹ nidi ọkọ. Orire nla si ni ẹniti a ba fi awe afọmọ ọpẹ ta lọrẹ ni, bakanna ni bi enia lala ri awe yi. Kabọ o alaiyeluwa ọba wa. Ọlọrun ko mase jẹki agba tan lori ilẹ.

## Egbogi fun arun ajakale ode yi

Ọtutu ni arun na kọkọ fi nbẹrẹ, ti gbogbo ara oluwa rẹ yio ku tuẹ-tuẹ, ki ẹniti o ba ti ṣakiyesi yi, mase jafara lati ma lo egbogi awonyi:-

Ginger tabi ata ilẹ jijẹ ati Atare, tabi ki a fi epo tutu pa gbogbo ara, tabi egbogi ẹrọ ni ki oluwa rẹ ma lo.



# Alapara Ibadan nki yin o

OKE FOKO
Ibadan

Gẹgẹbi mo ti sọ fun yin wipe ni ọsẹ yi emi Alapara Ibadan yio tun fi ẹnu kan ọrọ awọn alamulẹgbẹ mi ti a npe ni Ọyọmisi ni iwọn'ba ṣoki. Bẹni, ṣugbọn ki nto ma ba ọrọ mi bọ mo fẹ ki ẹ ba mi ka iwe wesiku kan ti mo ri gba lati ọwọ ọmọ Ọyọ kan ti o ni oruko on nje Layiwọla. Alufa sọ ọrọ, ọjọ ku, o ni Ọlọrun jẹri on, jọ ọwọ ẹ ba mi ka iwe Layiwọla, ọmọ "Ebiti ti kogboju ko le pa igbin".

Ojotu ẹ jọwọ ẹ ba mi mu iwe yi fun Alapara Ibadan, emi na ko mọ ibiti ngo dari iwe na si ti o le tete tẹ wọn lọwọ ju ọdọ yin lọ.

Ọgbẹni Alapara Ibadan, ẹ se pupọ, ọmọ Ọyọ ni emi, mo si ri nkan ti ẹ wi nipa ilu wa. Eko ni mo ngbe, mo si ti de ilu yi pẹ die. Ki a ma puro ninu ẹgbẹ Parapọ gidi ni mo wa Oju ko ti mi lati sọ, eyiti o ti mi loju ni nkan ti mo ri nile Ọyọ ti mo lọ ni aipẹ yi.

Awọn Yoruba ti o nl orin lo aṣiwaju ọtẹ ko puro, ọtẹ papa ni baba fọlufọlu. Mo se akiyesi wipe ọtẹ nfẹ mu ilu baba mi lọ s'ẹhin. A ni awọn ọmọ to jinna ninu ẹkọ, ọtẹ yi ko jẹ ki a moju to eto ilu. Gbogbo ọpọlọpọ ile ni o ndi ahoro. O da bi ẹni wipe a fi gbogbo nkan ti a ba se silẹ ni aisẹ. Gbogbo nkan ti ilu iba ma jẹ anfani rẹ ni rere ni arin ilu, ọtẹ ko jẹ ki owọ awọn oṣelu tẹ. Alagba kini ẹ ri si eyi?.

Gbogbo ilu ajoji ti mo nde ni mo ri pe wọn ntun ile ọla ṣe, Ibadan ngbero lati kọ Afin fun Olubadan. Tiwa ti o sọ ndi arugbo, kilo ṣe ti a ko le tunṣe? Iyẹn wa lọwọ awọn igbimọ wa.

Iwa Awe ni a bi mi, Akinmọrin ni a wo mi dagba, o yẹ ki o kuro ninu wa. Aye ti lu jara wọn nisisiyi. Ẹ jọwọ Alapara Ibadan, ẹ ba wa tun ilu wa ṣe o.

Ọgbẹni Layiwọla, e ma ṣe o, ṣugbọn emi Alapara Ibadan ko mba wọn ṣe ilu. Egun-komọkan ni mi, ti o ni on mba wọn ṣe ilu; mo ṣe bi ninu owo aimọkan ti mo nda ni awọn kan fi nra fila oniko ati ẹwu alukinba ni Makka. O dara ṣa, ọbọ idere fẹ gbọn na. Ọrọ niyi o, ẹnyin Ọyọmisi.

BALẸ FIDITI

Ki nto muẹnu kuro ninu ọrọ Ọyọ, o yẹ ki nki Babayeye, Ọba Gbadegẹsin, Ladigbolu Keji, ku alejo Balẹ Fiditi tuntun, Ọgbẹni Oyelakin Ogundele ti a ṣẹṣẹ fi jẹ ti o gba mi ni alejo ni aipẹ yi, Babayeye, ẹ ku alejo. Ade a pẹ lori bata a pẹ lẹsẹ o. Balẹ Ogundele agba dọ̀ vọ rẹ o; a ki ri kekere Balẹ. Emi Alapara Ibadan ko ni pẹ wa bẹ yin wo ni Fiditi ile iyan ko l'ọbẹ. Ṣugbọn ki ẹ tọju odo iyan kan silẹ fun mi pẹlu ọran igala ati ẹmu mẹta.

Iyẹn ki ṣe owo agbatẹlẹ o, nkan alejo ni

## Itan Perseus

Lehin ti Perseus ti fi ida Palas Athen ge ori Gorgon tan, 3ata ese re, bere si ere gbeiyefo. O wipe Gbe mi fo daradara, nitori oja iku mbe ni gigirise mi.

Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS



*Read this list of popular titles*

JZ 6077-Omosola Savage/Igba Laiye
" 6078-Aiye Akamara/Iwa Rere Leso Enia
" 6079-Gbo Adura Wa Baba/Irele Lo Laiye
(Rosey Show Mambo Orch)
" 6080-Gba Wa Lowo Ota/Iberu Olorun S. O. A. Ladipo and His Keranic Group
" 6082-Olomo Lo Laiye/Fuso Jaiye
" 6083-Shogbola/Wellington
Ade-Ade & His (Juju) Orchestra.

JZ 6088-Owo Lowo Agbara Ko/ Abiba Alaso
" 6087-Ori Lo Yomi/Saka Ilorin
Aminu Olaribigbe & His (Sakara) Band
" 6089-A Gbere Wa De/Awon Kokokoko-
Taibus Abuus & His (Apala) Band
RJZ 100-Ma Pami/Zambesi (In Afro-Cuban)
RJZ 101-Bowo Ba De/Adaku (Ibo)
RJZ 102-Ma Doyinbo/Igbuem Iwem ((Itsekiri) (Ibo)

*Sold by all the best stores*

"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow Label* RECORDS

HIS MASTER'S VOICE

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# Awon Oyinbo ri ilu Ilagida

Gbogbo enia lo ti ngbo itan kakiri nipa ilu kan ti nwon npe ni Ilagida. Awon opitan so wipe, nwon te ilu na do si eti ilu Ife. Oruko oba ilu na ni nwon npe ni Tai.

Nwon so wipe, ne ni ilu Ilagida ri si abe ile ninu isele nla kan ti o kari aiye.

Lose to koja lo yi nigbati oyinbo kan ti o nse oluwadi awon ohun Atijo fi nwa ile ni nwon ri aropo-dogiri ara awon ile ti nwon ko sinu ilu Ilagida.

Nwon fi ye wa wipe idi re ti nwon se npe Ilagida ni ilu awon Omugo ni wipe, laiye igbani, bi o ba ye ni Ile Ife, nibiti Odudua gbe fi se ibujoko awon ara Ilagida ko gbagbo pe enia tun mbe nibomiran.

Tai ni oruko oba Ilagida Olofin ni oruko oba Ile Ife nwon je olojo dudu, ogbon ko si tile ti ide inu aiye.

Nigbati Odudua de ti oju awon ara Ife bere si mole nwon wa bere si kegan ilu Ilagida.

Odudumudo ti o mu ase ewe jija bo lati ode orun, tibi, tire nilu Ilagida lo de si.

A gbo wipe nigbati isele yi je tan ni Odudua de, awon ti o seku ti o sa asala kuro lowo isele tuka seri ile, ogoro won lo ba Alaketu kuro ni Ife.


## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun German to sese de, fun oniruru aisan tokun tobinrin. Tete wa ra tiyin k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos


# Ede koyede lori oye oba Deji

AKURE. Irohin kan wa wipe, lehin iku Oloye Alaiyeluwa Deji oba ilu Akure ni awon enia ilu na fi ohun sokan, ti nwon si yan Ogbeni Ademuwagun ti o nse okan ninu awon Amofin ile Nigeria sori ite oba ti o ku na. A si gbo nigbana wipe, oba titun na si nse eto lati wuye.

Sugbon irohin tun kan wa wipe ko je wipe Loya Ademuwagun ko ni eto si oye oba Akure, sugbon o ni agba niwaju, ti nwon jijo je omo baba kanna. Bawo lo ha ti se to wipe ki a fi eni iwaju sile ki a si ma se eni ehin ni rele?

Nigbati oro yi nfe da akitiyan sile ni Oloye Rotimi, ti o nse eto ilu gbogbo yan oyinbo kan ti nwon npe ni W. S. Smith lati lo se iwadi oro na nilu Akure, lati le mo taani oye na tosi gegebi asa isedale won. Ki a to ko riwo-riwo oro na de odo Gomina kekere ni Ibadan, fun epa ase, ki otite ni le gori re?

## IWO TA NI YEN?

Ajese — Menuwo?
Hausa — Wo ni ni?
Ife — Yesireni?
Oyo — Iwo ta nu-un?
Egba — Iwo leyen?
Eko — Iwo ta niyen?


HINDU SANKARA'S

**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Yogic Powers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose ... order by Air Mail for Catalogues and Lamps ...

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England


No. 73/S.2/Vol.VIII/496

## Western Region Government

VACANCIES FOR CONFIDENTAL SECRETARIES GRADES II AND III AND STENOGRAPHERS

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment as Confindential Secretaries Grade II & III and as Stenographers in the Public Service of the Western Region.

| POST | Scale of Salary |
| --- | --- |
| STENOGRAPHERS: | D.2,3,4 (£207-£234x12-330 x15-360;£390x18-444x 24-492). |
| CONFIDENTIAL SECRETARY GRADE III | C(E) 1 (£390x18-444x24-492) |
| CONFIDENTIAL SECRETARY GRADE II : | C(E) 2 (£540x£24-588; £660, £684, 714. |

The post is pensionable and in the case of a new entrant into the Government Service, the appointment would be on probation for three years.

For further particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 36 Vol. 6 Notice No. 741 of 8/8/57.

Closing date: OVERSEAS CANDIDATES 3/9/57.
All other Candidates 7/9/57.

No. 73/S.2/Vol. VIII/496.

## Ministy of Education Western Region

### Vacancies for Clerical Officers and Clerical Assistants

Applications are invited from candidates with Clerical experience for posts of Clerical Officers and clerical Assistants in the Inspectorate Division of the Ministry of Education:-

qualifications:-
- (a) Clerical Officers –
  - (i) Cambridge School Certificate
  - (ii) West African School Certificate
  - (iii) General Certificate of Education Ordinary Level with a pass in at least three subjects.
- (b) Clerical Assistants –
  - (i) Certificate of completion of Class IV in an approved Secondary Grammer School.
  - (ii) Government Middle IV Certificate
  - (iii) R.S.A. School Certificate.

For further particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 36 Vol. 6 Notice No. 745 of 8/8/57.

Closing date – 31/8/57.


## Imoran rere fun gbogbo enia

Dajudaju bi kidirin inu ba nise daradara lo nmu alafia ba ara enia. Bi kidirin inu re ko ba sise dede tabi amodi nyo e lenu nipa aiko sise deedee kidirin re – aisan bi Ehin-didun, Lakuregbe, ara riro l'orikerike, Isete ati awon aisan bawonni:- A gba o ni imoran ki o lo egbogi yi:-

### Pilules V. E. Doumer

Egbogi ajebidan fun aisan kidirin yi je ti awon Faranse. Ojulowo kogemani ninu ile ni fun gbogbo ebi.

Sile meta (3/-) pere ni. Fi owo oko si.

**French Medicine Stores,**

8, Marina Street, Lagos. Phone 23264.

# E L E T I Ọ F E

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. IX. NO. 534, LAGOS, SATURDAY AUG. 24. 1957


## Dani-dani ki ba'ni l'agba

Kekere l'o ti mba wọn lọ, ni owe Yoruba ti a fi ṣe ẹṣin wosika wa ọsẹ yi, lori aṣayan ọrọ wa nipa iwa ti a nhu gẹgẹbi ọmọ enia lode aiye wa yi.

O jẹ otitọ ti o farahan gedegbe wipe ọpọlọpọ awọn enia ti o jẹ agbalagba lo ma nlọwọ ninu iwa buruku ati asan aiye. Ẹnikẹni ti a ba si ri ti o hu iru iwa bawọnni, bi a ba wadi rẹ wo, ao ri eye wipe ko nṣe ọtun iwa lara oluwarẹ bikoṣe wipe o ti nhu iwa bẹ lọjọ ti o ti pẹ, tabi lati igba ewe rẹ.

Kosi ẹniti o le jiyan rẹ wipe ko nṣe iwa bẹ l'o nti wọn de ibi iparun, ati ara ati ọkan pẹlu. Nitorina, ki olukuluku enia tọju iwa rẹ, nitoripe iwa ko ni fi oniwa silẹ, iwa enia ni yio fi iru ohun ti oluwarẹ jẹ han. Eyi ni Yoruba fi pa l'owe wipe:-

"Dani-dani ko mba'ni l'agba, kekere lo ti mba wọn lọ."

---

## ANFE ASOJU

A nfẹ Aṣoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ọfẹ lati fi kun awọn Aṣoju wa ni awọn ilu ti a daruko ni isalẹ wọnyi:-

Abẹokuta, Ijẹbu-Ode, Ijẹbu-Igbo, Ile-Ifẹ, Oshogbo, ati Port Harcourt.

Ẹ kọwe si Olotu Iwe Irohin Eleti-Ọfẹ, 28, Kosoko St. Lagos.

---


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun oti tu, ikọ ati oriṣiriṣi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Ero Ti o Nse epo Pupa



Ẹrọ ti o nṣe epo pupa ti ijọba Iwọ Orun nlo lati ma fi ṣe epo pupa ni a nwo ninu aworan yi. Ẹniti a nwo ninu aworan na ti o duro ni ọkan ninu awọn olori ibi iṣẹ ẹrọ epo pupa na, o fẹ lati yẹ epo na wo yala o jina tabi ko jina.

Ẹrọ epo na wa leti Odo Ọṣun lọna ilẹ Ijẹbu. Eyi ni ẹrọ ti o nṣe e, ko nṣe eyiti o nfọ ọ.

---

No. 115

## Federal Engineering Scholars

The policy of the Federal Government concerning the futher training of Federal Engineering scholars due to complete pre-engineering courses in 1957 is as follows :-

(a) Federal Engineering scholars at University College, Ibadan, who are successful in the Intermediate B. Sc. examinations in 1957 will complete their studies overseas;

(b) Students at University College, Ibadan, who pass the Intermediate B. Sc. examinations in 1957, and for whom admission to an overseas institution cannot be obtained for a course beginning in 1957, will, it is hoped, be placed in overseas institutions in 1958;

(c) Students who fail the Intermediate B. Sc, examinations in 1957 will not be allowed to complete their studies overseas. Further consideration by the Federal Scholarships' Advisory Board will then have to be given to their future;

(d) Federal Engineering scholars at the Nigerian College of Arts, Science and Technology taking the General Certificate of Education (Advanced Level) examinations in 1957 will not be placed in Institutions overseas but will complete their studies as far as possible at Nigerian College of Arts, Science and Technology.

2. It is emphasised that this policy is being adopted in 1957 only.

# Oro Oko janto-janto

IBADAN. Sanusi ti o jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ile ẹkọ Unive sity ni Ibadan ṣe pẹkirẹki pẹlu ọrẹ rẹ obinrin ni Orita - mẹrin nitu Ibadan; eyi ni ọrọ ti awọn ba ara wọn sọ.

**Sanusi-** Tilẹ wa nihin na, Grace, ọrọ tirẹ yi ma nfẹ ṣu mi, bi enia ba ṣa ti ba ọ sọrọ, ako apara ni iwọ yio fi dahun, ni ọjọ wo ni ao ṣe iwọnyi gba ?. Bi o ba tilẹ fẹ joye abuni bi eni la oyio, ṣe iwọ yio jẹki a g b e aṣedn tan ki o to ma ṣ e gbogbo iwọnyi !.

**Grace-** Tani sọ fun ọ pe iru iwọ yi ni emi yio fẹ lọkọ. Bi o ba yẹ ni fifẹ ti o sọ pe o nfẹ mi, kini mo gba lọwọ rẹ ri. Ọkunrin ti yio ba fẹ ọmọ dara-dara bi iru awa bayi, ni lati ni iṣẹ atata lọwọ ki ọkan obinrin n a le bale wipe on yio ma ri onjẹ lasiko ni wọn igbati iṣẹ ti wa lọwọ ọkọ rẹ.

**Sanusi-** Ha ! bẹni, iyawo mi, ọpọlọpọ ayo l e mbẹ niwaju f u n m i ṣugbọn ako mọ i r u iṣẹ ti ngo mu.

**Grace-** Jọwọ ma pa mi lẹrin lasan o jare, I w ọ k o mọ iru iṣẹ ti o lowo leri, ti awọn iya a t i baba wa yio dunnu si.

**Sanusi-** Ṣe nitoripe baba wa ninu iṣẹ ijọba lo ṣe sọ bẹ, iwọ ko ha mọ pe ati ibikan ni a ni lati bẹrẹ na ki a to de aye nla ?.

**Grace-** Bẹni ọrọ ri, bi ko ba si iya mi ni, baba mi ko ni wọ iṣẹ ijọba bakanna bi tirẹ ni baba mi bẹrẹ igbesi aiye tirẹ nje iwọ wo iru ipo ti baba mi wa loni.

**Sanusi-** Ṣugbọn emi ko fẹ iṣẹ ijọba, mo nfẹ kọ iṣẹ ti ara mi ni.

**Grace-** Hẹn ! iwọ k o fẹ iṣẹ ijọba ti o j ẹ p e lọdọdun ni iwọ y i o magba ọkunwo, i w ọ ni le ri aiye lati kọwe

(Wo yoka loju ewe keje)


## E ma ka Iwe Irohin Eleti-Ofe ki e si ma polowo oja yin sinu re.



**Ohun mimu ni alẹ**

*-fun agbara ni gbogbo ọsan!*



Ife Ovaltine kan daraju gbogbo nkan lọ ni mimu ki enia to sun. O b'ara mu o si nṣẹki ara sile o si nmu ni sun orun ti o gbadun. Ni ẹṣẹkẹṣẹ ni Ovaltine si ti nfi okun fun ọpọlọ ori ati ara. Wa a ṣi dide pẹlu ara sisile, ati agbara titun, wa a si wa ni imura sile lati yanju gbogbo nkan ti o fẹ fi ọjọ na ṣe.

*Awọn ohun ti nwọn fi ṣe Ovaltine ni ẹyin, irugbin ati mara, pẹlu nkan ti nfun ni ni agbara. Ohun mimu aladun ati onjẹ ti nfun ni ni agbara. Mu Ovaltine lale fun agbara ni gbogbo ọsan.*

# OVALTINE



O JẸ ONJẸ—MIMU TI
O PE TI O SI DARA PUPO

## Obinrin Nilati Sin Olorun Pelu Oko Re

Oleto,

Jowo gba mi laye ninu iwe irohin re oloyinmomo lati fi oro inu Alukurani Mimo yi ban awon eles'n kiriyo ati Imale lati ma se akiyesi iwa won si awon obinrin. Iwe Alukurani Mimo so ni ori 33, 35 bayi wipe:-

Olorun ti pese iforiji re, ati ere nla fun elesin ododo, lokunrin ati l'obinrin Onigbagbo tokunrin tobinrin, olotito enia tokunrin tobinrin, Onisuru; ati Onirele tokunrin tobinrin, awon ti o ngba awe, ti o ti ko ara won kuro ninu agbere sise, iru awon enia awonyi yio gba ere nla nikehin ojo. A ri nihin wipe Olorun ko ya enikan soto, tokunrin tobinrin lo wi.

Iwe mimo bibeli so ninu Iwe Korinti kini 7 1-2. Ohun ti o dara fun okunrin nipe, ki o mase sina, ki olukuluku kuku ni iyawo tire fototo.

Anobi Muhamed so bayi wipe, ninu ohunkohun ti o ba nje ni ki o fun iyawo re je, bi o ba da aso fun ara re, o ye ki o ra fun iyawo re pelu, nitoripe ki okan re le bale lori won, iwo ko gbodo lu u, de ipo ti iwo yio fi gba loju, iwo ko si gbodo fi orun le niya.

Mase lo awon iyawo re ni ilo eru, sugbon ki o fe won gegebi iwo ti feran ara re nitoripe awon ni iya re, omo re ati anti re.

Ile aiye ati ohun gbogbo ti o mbe ninu re lo niye lori sugbon obinrin to ba ni iwa rere sowon gogo ju gbogbo re lo. Okunrin ti o ba se orire tobe ti o si lobinrin oniwa rere dukia nla nla l'o ni.

Onigbagbo ododo kan ko gbodo korira iyawo re, nitoripe bi o ti le je wipe iyawo na nse e louu kan, daju-daju, o sa ni ona miran ti iyawo na fi nte e lorun.

Nitorina iwe Alukurani Mimo so wipe, ki gbogbo awon ti o nhu iru iwa awonyi yi pada, ki awon si wa aforiji lodo Olorun, nitori ki oluwa re ba le serere, 34, 31.

Emi ni
Lemomu Ajakuta

## Itan Awon Ore Meji

Lati owo Y. A. Braimo

Awon ore meji kan wa, okan je Olowo, ekeji si je Oloogun ekini bimo, beni ekeji pelu. awon omo mejeji nwonyi si tun je ore. ilewe kanna ni awon nlo.

Bi omo Olowo bi nlo si ilewe yio mu owo ina dani sugbon omo Olo-ogun ko nri owo mu dani. Lojo kan omo Olo-ogun lo ba baba re, o wi fun pe, Baba! nko lo silewe mo. Baba re dahun pe kini nje be? o ni lati ma lo. Baksnna ni omo Olowo so fun baba re pe, on ko kawe mo.

Baba re fi owo pa l'ori, o dahun pe ko buru, on yio si sobu fun u. Olo-ogun ni ki omo on si ma lo si lewe, be, be, omo ti Ologun ka iwe mefa. Sugbon baba re tun so fun pe, owo ilewe kolti su on ni sisan, ki o tun lo se idanwo nilewe giga.

Laifa oro yi gun, omo ti Olo-ogun yege fun eko olofe, eyiti awon ape ni (Scholarship) awon si ran lo lati ko ise isegun nilu oyinbo. Nigbati o se, omo na yege, o si pada wa si ile. Nigbati Okunrin Olowo yen ri gbogbo ohun ti o sele yi, o so fun omo tire na wipe, ki on na lo se idawo fun eko olofe, nse lo ja kule, Okete ti bo iru mo ode lowo.

Gegebi owe Solomon, o wipe, omo ti o ba gbon l'o nmu inu baba re dun sugbon eyiti o go, inu iya re ni yio ma baje. Enyin okawe wa ohun ti itan yi kowa ni oro ti o jade ninu iwe orin Solomon bayi pe "Ko omode, nigbati o mbe ni ewe, ni ona ti yio lo nitori nigbati o ba dagba tan ki o ma ba ya kuro ninu re". Abo mi re o.




### AKIYESI PATAKI

Enikeni ti o ba fe ra Iwe Irohin Eleti - Ofe Ki o lo si Idi Moto, Ogunpa, Tabi Lodo Asoju Wa, Ni 107, Oke Padi, l'egbe Sosi Aguda Nilu Ibadan.

# Ebun Nla

## Wa je 375,000/- ninu

Orire ti o tobi julo ni EAST

Eniti o ba yege ninu orire na yio je 355,000/- eniti ila kini ati ekeji tire ba dogba po pelu tiwa yio je 20,000/-

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | | |
| | | | |
| | | | |
| | | | |

Șe eto awon nomba lati 23 si 38 ninu ojule kokan, ti aropo re lati otun si osi, lati oke sisale lati igun kini si igun keji yio fi je 122. A ko gbodo lo nomba kanna lemeji.

Ojo ti ako ni gba iwe lodo enikeni mo ni 26/9/57. Ẹ fi gbogbo iwe ayin ran oko ofurufu. Esi re yio jade ni 30/9/57.

| Last Result Total 118 | | | |
|---|---|---|---|
| 23 | 26 | 32 | 37 |
| 33 | 36 | 22 | 27 |
| 34 | 31 | 29 | 24 |
| 28 | 25 | 35 | 30 |

Owo eyo kan 25/-. Fun merin 45/- Fun merin-dilogun 80/- Fun merinlelogun 100/- Fun mejilelogbon 120/- ati bebe lo.
OFIN:- Ẹ le se pupo sinu iwe miran pelu owo re ni pipe, so gba. Ẹ le fi owo ranse ni iwe owo ti (Postal Order tabi Money order) Nomba ti Gesi ni a fe.

Eniti orire tire ba dogba po pelu tiwa ni so gba pe o yege Eniti o ba fe gbo esi ki o fi 1/- owo oko kun owo tire, sugbon bi o ba fe gbo kiakia fi 2/- owo oko ofurufu kun owo tire. Ko si eje nibe, eyi ti a ba se ni abe se.
Fi owe ati orire tire ranse si:-

**EAST ASIATIC CORPORATION**
P. O. 13, ALIGARH (INDIA)



No. 73/S.2/VoL. VIII/496.

# Ministry of Education-Inspectorate Division

## VACANCIES FOR SUPERVISING TEACHERS

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Supervising Teachers, Ministry of Education, Western Region, Ibadan.
Salary :- Scale C(E) 1,2 : £390x18-492; £540x24 -588, £660, £684; £714.

For further particulars and Method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 36 Vol. 6 Notice No. 744 of 8/8/57.
Closing Date: OVERSES CANDIDATES 31/8/57
All other Candidates 7/9/57.


# Oro Oko janto-janto

(O bere loju ewe karun)

siwaju nisise bayi iwo yio di oga agba nibi ise; bi o ba si sorire o le gba ibe di Engineer Chemists Architect Lawyer ati Scientist.

Sanusi- O dara iyen ni pe iwo ko gbado pe mo tun le ri owo se gegebi ti baba re ninu Ișe miran. Jeki nso fun o bi mo ba lo si Oke okun Oke Oya tabi si Saro mo le di Salesman Kapinta Electrician Tailor Șoja tabi Atuko ni won igbati awon enia ba ti gbadun ise mi.

Grace- Eyi ti o wi yi le je be, sugbon ko le jeki a tete ra ile bori. Iwo ko ha gbo nipa owo yiya ri? anfani ti eni ti ko si ninu ise ijoba ni nuni. Bi eyiti mo wi yi ko ba da o loju bere lowo iya mi yio si la o loye.

Sanusi- Jeki nfi asiri mi han o, aye ise ti si sile pupo fun mi nisisiyi fun Std mewa ti o si ni L.M. Mo ti fi 'oruko mi ranse, nilu Kano ni ao lo sise lodun to mbo.

Grace- Ha! oko mi, o ti good to.

# E fi egun otelo to o.



Irohin ti a gbo ni wipe edeaiyede ba sile larin awon Omo egbe Action Group tilu Warri pelu Ogbeni Arthur Prest.

# Jesu Ti Le Aiye Ni Tabi Ti Orun?

A gbo lenu awon alufa ijo Kiriyo wipe, nwon ri ka ninu iwe Bibeli wipe Jesu Christi, nigba aiye re, so fun awon omo ehin re pe, on yio ku, on yio si ji dide lojo keta. O tun so siwaju wipe, lehin ti on ba ji dide tan, ase ni on yio goke lo si Oke orun.

Șugbon lehin ti on ba ti goke lo si orun tan, on yio tun pada wa. Awon omo ehin re tun bere wipe, yio ti pe to? O si dahun wipe, on ni yio de kehin ki aiye to pare. Șugbon e ma sona, ki e si ma sora, nitoripe, opolopo enia ni yio ma pe ara re ni Jesu. Ẹ ma se akiyesi won, nitori nipa eso won ni ao fi mo won.

Ninu tira awon Imale, nwon ni, nigbati Jesu ba tun de nigba keji, Madi ni yio ma je. Gegebi Jesu ti so wipe opolopo ni awon eke Woli ti yio ma dide ti nwon o ma pe ara won ni Jesu.

Lati fi han wipe ododo ni oro na, a ti gbo larin ijo Imale nipe Madi ti Kadian, Madi Mesina Madi Alexandria ati Madi Khartoum. Ati larin awon ijo Kiriyo, a ti gbo nipa Jesu Agege, Jesu Ijebu-Ode, Jesu Ilesha, ati Jesu Kalaba.. Jesu ti aiye niwonyi ni, tabi ti orun?

(Wo yoku loju ewe kejo)

# Awure Bamwo




**Omo t'o mu Bamwo ki ku,**
**Omo t'o mu Bamwo ki s'okunrun........**

**The Egba Trading Aradan Stores**
18, Denton Bridge Street,
P. O. Box 2,
Ebute Metta & Branches
Phone 44153.


# Owe Ni Gbongbo Ese

Lati Owo Satis Pelogun

Awon baba wa lo ma npa owe wipe, "Owo ko nto enia, enia lo nto owo". Owe keji niyi wipe, "Iromi ko njo asan, bi ko ba si ohun ti o nlu ilu fun Iromi nisale omi". Gbogbo jan, jan, jan, ti omo enia nse labe orun ti awa yi, ko koja ala ori owo. Gbogbo lala-kolo-fefe ti enia nse nile aiye yi, bi a ba tan idi re wo, ko koja owo apekonuko.

Bi a ko si okun ju Christopher Columbus lo bi o si fo loju Sanma ju eiye Akuyele lo, bi arjo irin ajo tayo Oko Reluwe, bi a si se Alejara ju awon Ogoomoso lo, lori kini a nse gbogbo lalas awonyi si bi a ba tan idi re wo o an ti wipe agbata-gbagbo re ko tayo owo.

Bi enia ni apoti aso ki o to ti apoti medogun aso yio pa ojuwa re. Bi enia ba si bimo ki o to bi odunrun omo yio su Bi enia fe obinrin titi ki o to fe ogorun olomoge yio su Bi enia ni dukia ki o to ni apoti golu kan Eeda kan Ide kan baba kan Iyun kan Segi kan okun kan nse ni gbogbo re yio tile suu gogo. Bi enia si ni awon ohun osin ti Adie, Pepeye, Tolotolo, Agutan, Ewure, Malu ti o si ni enia ti o ntoju won nigbati o ba jeran-jeran titi ti eran ba li chin sibesibe, nse nigbogbo re yio su patapata.

Sugbon, owo nini ko nsu enia. Bi enia ni egberun poun lowo, bi epin ba sonu lowo re yio fere wa de Ilete. Lojo kan okunrin Olowo arakuyamu kan (Milonia) ti owo re ti koja eyi ti enia le siro, nkoja lo ni adugbo kan, bi o ti fe bo sile ninu Moto, beni o ri owo sile kan nile, o bere o mu o si ju sinu apo. Owo ko sa nto enia.

Enia bi aparo ni aiye nfe, ki iwo ma lo akisa lojojumo ki on si Joye Daily Woolen. Olowo ko fe ki a ri elomiran ti o le se inu okan ti on olowo ti se. Bi enia mo fari ati afe ni sise bi enia le ja pupo ohun kohun ti o wu ki enia le mo se pata-pata pinra re ko tayo owo aitorina iwo ore mi owo ni gbongbo ese.

# Jesu Ti Le Aiye Ni Tabi Ti Orun?

(O bere loju ewe keje)

Idi re ti a ti bere bayi ni wipe gbogbo awon aso tele ti Jesu paapa so, a koiti ri okan ki e sele. O si daju wipe gbogbo awon Jesu ti a daruko uwonyi lo si mbe nile aiye ti awon na si tun nfi eni gbo pe Jesu miran tun dide

Sugbon a ti so tele wipe ki e ma sora, ki e si ma se akiyesi won, nitoripe nipa eso won ni ao fi mo won.

## AJAKALE ARUN TUN WO'LU EKO

(O bere loju ewe kini)

Ki Oluwa jowo tete ba wa dawo re duro.


117

# Army Entrance Examination For Potential Officers

Applications are invited from persons wishing to be considered for entry into the Royal Military Academy SANDHURST, with a view to becoming Regular Officers in the Nigerian Military forces (Royal West African Frontier Force).

Thirteen vacancies at the Royal Military Academy are allotted annually to Nigerian Cadets and applications to fill those vacancies are called for twice a year.

CONDITIONS FOR NEXT ENTRY.

Applicants must fulfil the following conditions:-

(a) Age - Over 17 years 2 months and under 22 years of age as at 14 March 1958.

(b) Medical - No physical disability.

(c) Education - The General Certificate of Education (or equivalent) in the English language and three other subjects

EXAMINATION

With the exception of applicants who hold a Universitty degree all candidtes will be required to pass a written examination. The next written examimation will be held on Wednesday 18th and Thursday 19th Dec 57 at the following Centres-

LAGOS KADUNA ENUGU

Candidates will be examined in General knowledge, English and Mathamatics.

SELECTION AND MEDICAL BOARDS

Candidates who have passed the written examination and those who are exmept by virtue of previous scolastic attainments will be required to appear before a Force Selection Board at LAGOS, ENUGU or KADUNA and afterwards at a Medical Board at LAGOS or KADUNA.

TRAINING

Those candidates who successfully pass the Force Selection Board and the Medical Board will be enlisted into the Royal West African Frontier Force and will attend a 24 weeks course at the RWAFF Training School, Teshie, Accra; Ghana. If successful, they will proceed to the UK for pre-Sandhurst training and will then enter the Royal Military Academy, SANDHURST to attend the 23 months Officer Cadet Course. On the successful completion of this trraining, cadetes will be granted Queen's Commissions in the Nigerian Military Forces (RWAFF) and will receive an initial annual income of £666

METHOD OF APPLICATION

The names of applicants are required to reach Headquarters Nigerian Military Forces, APAPA, Lagos not later than 1 Nov, 57. Applicants must apply in writing and enclose a recommendation from a person in authority (eg District Officer, Minister of Religion, Doctor, Solicitor or Officer in the RWAFF not below the rank of Major). An application form, together with the examination syllabus will then be sent to applicants.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 23370